# DADA OWOLABI TABI O SUN NI, ORUN KE!

**Ikede**

Awo ikede yi f u n gbogbo enyin Okowe wa ati asojo wa eripe, eni kéni ti owo ba seku ti owo re ki o tete fi ransé nitori gbogbo ohun elo ti a fi ntéwe irohin lo ti gbe owo leri.
Sekeni ti ko ba fi tire ranse ao da iwe ré duro ao si sa agbara lati gba owo wa ni owo re. Olotu


# ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

ELETI – OFE

Gbarada, ti eleegan l'oku irohin aladun pelu oro abalaiye ni o mbe ninu Iwe Irohin Eleti - Ofe.
E ma ka losose.

VOL VII No 432 LAGOS (SATURDAY) OJO ABAMETA SEPTEMBER 10 1955, IYE OWO ELETI OFE KOBO MEJI. (2)


## Ejo Awon Apania Di Monday

### DADA OWOLABI, ABI OSUN NI ORUN KE!

Ejo awon ti a fi sun esun apania lori iku Odomokunrin Akorin Olohunyo ti oruko re nje Israel Njemanze ti aworan re mbe ninu iwe wa yi, ni adajo ye ejo na si ojo Monday to mbo, ti ise ojo kejila osu yi.

Ki Adajo to ye ejo si ojo Monday, o se ikilo fun awon Oniwe Irohin Daily Times wipe nwon nse afikun oro on, ati oro ti ko sele rara. Ekinni O ni Daily Times so wipe Ogbeni C.O. Madarikan, Agb'ejoro Ijoba gba on ni imoran wipe ki on bere lowo awon odaran bi nwon ba fe ki Ogbeni Munis (lawyer) se ejo won?

Adajo so wipe on ko fi igba kan pase fun Ogbeni Munis wipe ki o se ejo fun awon odaran na' nigbati ko fe lati se, o so wipe gbogbo irohin na je iro patapata, o si le fi ero aidara si okan Egbe awon agb'ejoro. (Members of the Bar)

Adajo gba fun Ogbeni Munis ki o yo owo kuro ninu ejo na, o si so wipe on yio so fun akowe Ile-ejo kio fi ise na fun awon Loya meji miran, eyi yio si gba asiko die nitorina, ki a fi riro ejo na si ojo Monday. Ogbeni E.A Tejuoso si gba be ati awon Loya elegbere yoku; riro ejo na le bere ni Monday tabi o pe patapata, ko ni koja ojo Wednesday ose to mbo.

Awon Odaran na ni:- Peter Nwangwu, Michael Adeyemo, Lawal Dada. Dada, Owolabi, Cyril Anikwe, Lamidi Ayinde Laye Adewale ati Samuel Jegede.

AKORIN OLOHUNYO



ISRAEL NJEMANZE



Aworan oke yi niti awon ti olopa ko fun esun apania ni akoko ki adajo to da enia mejo sile ninu won fun aiko si eri to daju lati bawon ro ejo Awon enia mejo ni o ku ti yio duro sonson niwaju ate Idajo.

Enia merindinlogun ni nwon mu fun esun ipania na, sugbon aworan ti enia mejila ni eri ya ninu won.

## Ogbeni Kola Balogun Ya Ope Si Oro Oye

Awon oloye pataki-pataki mejila ni nwon ko oro ti Ogbeni Kola Balogun so si oye Apesin ti oba Oshogbo fi Olola, Agborioye-joye Obafemi Awolowo je danu wipe oro ope gbaa patapata ni o so.

Won si fi han wipe oro alai-mokan ni oro na je nitoripe ni ojo iwuye ti Olola Awolowo se ni Oshogbo, ese gbogbo oloye agbegbe l'ope sibe, eyi to lati fihan enikeni dajudaju wipe oye na m'oke, o si duro sinsin.

### OBINRIN OJOWU KAN SE IKU PA ARARE

BOMBAY. Irohin kan wa wipe obinrin gbajumo kan ti o nse itoju awon aboyun ti o si tun je apogun (Dispenser) gba awon odomobinrin wundia sibi ise re gegebi olutoju awon alaisan lati mase itoju awon aboyun

A gbo wipe Dokita ni oko obinrin gbajumo na. Ni ojo kan ti Dokita na wa wo ibise iyawo re, lehin ti o lo tan, a gbo wipe obinrin na bere si ba awon omo ise re obinrin meta ja wipe nwon rerin si oko on. Eyi l'o fa ti obinrin na fi gbe orisi majele meta fun awon meteta.

Nigbati oro obinrin na dewaju adajo, o pase wipe ki a lo yegi mo obinrin na lese, on ni o si je obinrin ti a koko yegi mo lese nile India.

# Ile Ifiweranse Ilu Epe

EPE — Ni ojo keji osu yi ni alakoso ile-ise Ifiweranse (Minister of Communications and Aviation) Ogbeni K. O. Mbadiwe lo si ilu Epe lati lo si Ile-ise Ifiweranse (Post Office) ti ilu Epe.

Nigbati o si ile-ise na, o so ninu oro re wipe awon Alakoso ma nsaba doju won ko awon ilu nla-nla, sugbon on ro si eto pe awon ilu kekeke na nfe abojuto, eyi ni oro ti o mu on wa silu Epe-oro re yi dunmo awon enia ninu.



Qlola S. L. Edu ti ise Asoju Epe ninu Igbimo dupe gidigidi lowo Alakoso ati awon osise Ile-ise Ifiweranse fun gbogbo ilu Epe lori ile-ise Ifiweranse tuntun na, o si so wipe ilu Epe yio ma se'reti awon ohun anfani bawonni ni sise-ntele, gegebi ibere won gbogbo ti nwon ti se.

Qba Aialyeluwa Olu Epe ni o se ifilage ojo na, Qgbeni G. E. F. Harcourt, ti ise Ajele (District Officer) paapa wa nibe.

Ile-ise Ifiweranse tuntun na dojuko Oja ilu Epe.

# Mammy Water Wo Qkunrin Kan Sinu Omi.

PORTHARCOURT:- Okunrin kan, Samuel Okanlawon ni a gbo wipe o lo si ile faaji (Hall) ibiti nwon gbe njo ni ilu Portharcourt ni ipari osu to koja yi, nitoripe bi nwon ba sese gba owo osu, ni nwon ma nlo se faaji ni ile faaji yi.

Ijo yi bere ni dede agogo mefa irole ojo na, sugbon nigbati o di nkan bi agogo mejo abo, awon obinrin bere si wole lorisirisi pelu aso alarabara lorun won, omiran pelu Golu oniyebiye, bata Onide ati beebee.

Samuel kan dide bo si ita gbangba nigbati ori odomobinrin, eleyi-ju ege kan ti ko mo wipe "Mammy Water ni. Nwon jijo soro ile po, obinrin yi ba Samuel damoran wipe ki awon gba ategun de ebute ki awon le ri aye so oro dada. Samuel gba imoran obinrin yi.

Awon mejeji dori ko'na Ebute, nigbati nwon de eti Ebute nibiti nwon ti mba faaji igbadun oro lo, ni abami obinrin yi ti ra Samuel oko iyawo mo, ki a ma fa oro gun, o di juwa ninu omi, bayi ni Samuel pelu obinrin na fi ba odo lo.

Enyin odomokurin ti ko si obinrin ti e ko le po, e fi eyi kogbon o.


## IMORAN FUN ENYIN ABIYAMO

**Enyin abiyamo e wa ra OMORELA o dara pupo fun awon omode.**

A ma je ki omode ri orun sun daradara o dara fun olutu iko ati orisirisi arun miran ti o ma mba omode ja ni asiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe o dara pupo fun awon omode

**OMORELA BABY MIXTURE**

*(SILE MEJI ABO 2½d. FUN IGO KAN)*

O wa lodo :—

COMMERCIAL MEDICINE STORES

(Qualified Chemist)

10, VICTORIA STREET, LAGOS



BERE FUN **"AEROXON"**




OJULOWO EGBOGI Fun **Esinsin**, Yonmuyonmu, Kotonkan, Afopina ati fun Orisirisi Kokoro oniye ti o ba nje tabi ti o ba nta enia ni ara pelu. Orun Egbogi yi dara a si ma fa awon Kokoro wonyi lati wa to o wo. Bi nwon ba si ti ba le won koni le lo kuro lara re mo rara ni.

Price 6d Dozen 5/- Postage 1/6

Eyo Mejila tabi Jubelo ni ale fi ranse si Idale tabi si Ilu Okere rere o.

BERE NI SOBU:-

**WATERLOO MEDICINE STORES**

21, Obun Eko Street, P.O. Box 333,

Lagos, Nigeria.



## Mo Gbadun Siga Pirate




# PIRATE

**Je Siga To Dara**

## Irora Lakuregbe

Iwosan re lododo niyi. Bi enia ba nfẹ iwo an ti o daju kuro ninu irora Lakuregbe o yẹ ka tete fi egbogi yi ko loju. Nitoripe Kindinrin oluwa rẹ ko sisé to, o nfẹ iranlọwọ Nitori iru amodi bayi lati ṣe ṣegbogi DE WITTS, yio si fun enia ni igbadun ara.

Kakiri aiye ni egbogi yi ti nṣe iwosan fun Lakuregbe, dan wo ki o lọ ra ọkan ni ṣọbu egbogi



Ohun ti o nfa nigbati Kidinrin ko ba sise tara, sugbon bi enia ba ti lo egbogi yi alafia yio desi oluwa re, nitoripe ara Kidinrin ni yio ti xise. Danwo lo ra ni sobu egbogi.

**DE WITT'S PILLS**

for Kidney and Bladder Troubles


---

### ỌBALADE DI ỌDỌFIN ỌRANGUN

Ni ose tokoja ni Alaiyeluwa Ọba Orangun ti Ilu Illa fi oye Odofin Orangun da Ọgbeni Michael Bolarinwa Obalade ti ise akowe oluta-oja fun awon Ọyinbo onisowo ti a npe ni G. B. Ollivant l'ola.

Ninu gbongan Lisabi (Lisabi Hall) ni Ebute Meta ni nwon ti se eto Ifijoye na fun Ogbeni Olabode, O oye Babakekere Orangun 'ati Oloye O aloti l'o wa se if'joye ojo na, ile kun, ode ko gba ese fun opolopo enia to wa sibi ifijoye na.

Ogbeni D. A. Oyefara l'oka iwe ti Oba Orangun Illa fi ranse, o si so ninu iwe na wipe Oye Odofin ti on fi Ogbeni Obalade je yi je oye ti a ro si eto gegebi Ogbeni Obalade ti nsise rere fun ilosiwaju ilu re, ti o si ni ife ilu re l'okan gidigidi. Nitorina, eniti o ba se ni o si ni lati je.

Awon egbe ati Saraki enia ti o peju-pese sibe niwonyi:- Awon Egbe Shepberd Lodge ti Eko ati ti Ebute-Metta, Oloye Asajon Eko l'owa soju fun Oba Adeniji Adele, Ogbeni H.B. Phillips, T.B. Bankole, A.S.G Nelson, J.I. Ade. John, M.A. Banjo ati opolopo saraki enia l'okunrin l'obinrin ti ako la daruko tan.

Oye A mori o.


## SIMENTI TI OYINBO BURHAM NI A FI KỌ



### ILE EJO ILU ACCRA

Awon ile ejo ti a sese ko, nwonyi mbe li arin ilu awon Aganyin ni Accra, o si je apere ilosiwaju ti a se fun idagba soke ile enia dudu. Simenti Oyinbo Burham ti Portland se iranlowo gidigidi ninu kiko ile na ati awon ile nla nla miran yi fun iwon adorin odun sehin. O si ti fi han gbamgba wipe Simenti ti Oyinbo Burham li o lagbara julo ti o si daraju, on ni a si le gbekele ni gbogbo agbaiye.

**BURHAM**

PORLAND CEMENT

BURHAM BRICK LIME AND CEMENT Cº · LONDON · BURHAM WORKS · PORTLAND CEMENT

---

## Chairs For Rent

APPLY

**OFE**

NO. 3, AIBU STREET, LAGOS.

# ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS
28, Kosoko Street, Lagos
P. O. Box 467

CABLES & TELEGRAMS
"ELETI-OFE LAGOS"
Phone 23370

VOL. VII NO. 432 LAGOS SATURDAY SEP. 10 1955.


## Qjo Ki Ipe K'o Ma Ku Ola

Qro ejo iku Akorin olohunyo ti oruko re nje israel Njemanze tf adape re nje Nwaoba ni ejo na bere ni Kotu Ganran nisisiyi.

Enyin okawe wa, eyi ko ha to ironu fun eniti o moye bayi? nitoripe lati nkan bi odun melo kan s'ehin, a ko se odun kan dele, ki a ma gburo wipe nwon pa enia kan, ati pe ipa oro ni nwon pa.

Kini ohun to fa irufe iwa buruku yi de arin wa? iran "Karo, E o jire" jina si iwa ese yi laiye ijoun, sugbon bi asiko aiye tiwa yi ko.

E jowo, e je ki a ronu wo ki awon janduku enia ma so ilu wa l'oruko ti awon baba nla wa ko gburo ri, titi ti nwon fi teri-gbaso.

## Ariya To L'arinrin

IBADAN— Opolopo ariya ni awon borokini enia se fun Qgbeni B. Popoola ti Ekotedo ni Ibadan, eyiti nwon fi ki wipe odigb'ose nigbatio mura lati lo si ilu Oyinbo fun imo Eko giga.

Ko si botiri ni ariya na, o dun, o si larinrin; a fi eyi ki Qgbeni Popoola wipe a lo a dara abo yio sunwon o.

## OLORE KI IKU, ORIRE

Ologa Oloye Anthony Enahoro, Olotu Atunluse ti Ijoba Iwo-Orun ni eniti o un awon Egbe Mid-West Boys Scouts ni Ponwun mewa (£10) nibi ariya ti awon Boys Scouts na se ni lowolowo yi.

Oba Akenzua losi ipade ariya na, Oyinbo Ajele ti ilu Ibini (Benin) si ba won soro iyaju ati iwuri. Eyi wa o, Oloye Enahoro tiwa

## Elewon To S'alo Pada S'odo Qlopa

WARRI— Qkunrin kan ti oruko re nje Ben Warri, n eniti nwon ti ju si ewon odun merin, o si se nigbati o di inu odun 1945, ni Ben Warri ti sa kuro l'ogba ewon.

Odidi odun mewa ni okunrin yi fi nje alafia kiri ti nwon ko si ri mu sugbon funra arare ni o lo si Sabu awon Qlopa ni o ba so idi abajo gegebi on ti sa lo laiko lo asiko pe l,ogba ewon

Nigbati oro na de iwaju adajo, Ni Ben Warri ba so fun adajo wipe, on ni on fi ara on han awon olopa nitoripe awon ore on ma nfi bu on wipe ojo enia ni on niwon igbati on ko ti le duro lo asiko ti nwon da fun on pe l'ewon.

Irufe yeye be ko ba on lara mu ni on ba se kuku lo fi ara han awon olopa. Adajo ni ki o yara lo si ewon osu mejila.

Abo re o.

## Iyawo Di Kobo Ni Kano

Irohin ti a gbo lati Oke-Oya, nilu Kano, ni wipe awon Ijoba Ibile nle gbogbo obinrin ti ko ba ni oko kuro nilu won.

Oro wa di tulasi, opolopo awon obinrin ni nwon ti gba lati ni oko, ofin ti Ijoba Ibile se ni wipe enikeni to ba fe lati fe iyawo yio san Sisi (Sixpence) yio si mu eyito ba wu u, O di oni-iyawo niyen.


## BIG OFERS FOR PRIZE WINNERS

Puzzle No. 329

| | | | |
|---|---|---|---|
| | | | |
| | | | |
| | | | |
| | | | |

Total :— 64

Guide 329

| | | | |
|---|---|---|---|
| 18 | 13 | 15 | 12 |
| 8 | 19 | 9 | 22 |
| 11 | 16 | 14 | 17 |
| 21 | 10 | 20 | 7 |

**£2,000** for each all correct.

**£100** for one error.

**£1** for each three errors.

Arrange numbers in the Squares of Competitions No. 329 or 330 in such a manner that when added horizontally, vertically diagonally, the total should come to 64 (sixty four) and 195 (one hundred and ninety five) respectively. In case of the Competition No. 330, the position of number 60 (sixty) should remain unchanged. Each number should be used once only.

Entry Fees:- Sh 3/- for one entry or Sh 20/- for nine entries or £10 for set of ninety entries for individual Competition.

CLOSING DATE (from your place) 15-10-55 By air mail

RESULT:- 2—11—55

Puzzle No. 330

| | | |
|---|---|---|
| | | |
| | 60 | |
| | | |

Total :— 195

Guide No. 330

| | | |
|---|---|---|
| 74 | 60 | 40 |
| 24 | 58 | 92 |
| 76 | 56 | 42 |

**£2,000** for each all correct.

**£100** for one error.

**£1** for each three errors.

Rules for both the Competitions:- Competitors can send any number of entries for both or any of the Competitions with the requisite fee by uncrossed British Postal orders or Bank drafts payable to the ASIATIC FINANCE & TRADING CORPORATION, NEW DELHI-5. (2) Entories are accepted on blank papers and must be written in English Figures. (3) An all correct Solution will be that which will be similar to our official Sealed solution, (4) Send Sh 1/- more to get the official solution by air. (5) Corporations decision will be final and legally binding upon all the Qompetitors in all respects.

Post your entries with fees to:-

ASIATIC FINANCE & TRADING CORPORATION (329/30 Co)
RAJINDAR NAGAR NEW DELHI-5, (India)

ASO ENIA KUKURU DI GUNGUN

Bi iwo ba nfe ki o gun die si (I crease Height) kowe fun "ILANA TO DAJU" lodo wa. O dara fun Okunrin ati Obinrin.
Fi Ogbon Sile (30/-) sinu iwe re, ibase Postal Order, Bank Draft. tabi SEKI Aristin-Ajo ti Gesi tabi America, Ao Gba.
ADDRRESS:-
ACTIVITIES (D 240)
KINGSWAY, DELHI-9, INDIA.

NOW,
AVAILABLE

BUGLES, BEDSTEADS
PAINTS DISTEMPERS,
SAFES Etc.
Just write, Call, or
Phone 21372
IKORODU TRADING
COMPANY
20/28, Balogun Street,
(P. O. Box 395) Lagos
AND
NEW COURT ROAD
IBADAN

## Ọlopa Ko Awon Sasawere

**Kano** Irohin ti o te si wa l'eti ni wipe awon omokunrin wewe kan bi omo olodun mefa de omo olodun mejo, ni ojo ori won, ni won lo ko arawon jo, lati se ipade Oselu ni Kano. (Political Mass Meeting)

Awon sasawere Oselu omo wonyi nkede wipe awon nfe "Sawaba" eyiti itumo re je ominira, nigbati Ọlopa y o lorere, awon omo na bu rele, nwon sa lo, sugbon akonije won duro, ko sa.

Asia won to nfe lele l'oju Orun, awon Olopa mu lo. Gbogbo enia ni o nso wipe o ye ki a tete te gasi awon omo to fe gba eko si ona-odi yi bo awo, ki nwon ma ba di ijogbon lehin ola.

AFUN NI L'OKUN ARA

Bi iwo ba ru (THIN) o le san'ra ki o si l'okun ara to bi iwon okuta mewa de Ọgbon tabi jubelo
A ti se awari ona eyi, kowe si wa, ki o si fi Sile meji (2/-) sinu iwe re lati so ara to fuyi di olokun-ara.
ADRESS:- A CTIVITIES,
KINGSWAY, (T140) DELHI- 9,
INDIA.



Awọn
enia pataki
ni nwọn nmu
OVALTINE
Aladun




Ovaltine jẹ onjẹ ti nmu ara awọn ọmọde gberu, o jẹ iru awọn onjẹ ti awọn ọmọde fẹ lakoko igbayi ti yio si ma fun wọn ni ọpọlọpọ agbara ti yio si ma jẹ ki nwọn ma dagba pẹlu alafia ati abgara lati di awọn oṣelu ọla. Ovaltine ni o jẹ ohun mimu ti awọn ọmọde fẹran ju ti o si dara fun wọn lati ma mu ju nkan mimu miran lọ.

*Fun wọn ni "Ovaltine Biscuits" pẹlu, nwọn yio si fẹran rẹ.*

**Ovaltine**
**nmu alafia, agbara ati emi gigun wa**

**Always Read And Advertise, In Eleti-Ọfe**

# Ola Oluwa Ko Ntan

Lati Owo Eso Ikoyi

Ohun gbogbo ti enia ba se lona eru, tabi lona aito, ni a npe ni aisododo. Owo ti enia ba fi ona eru, tabi ona aisododo ni (ru Owo tabi oro bawonni ko mba ni kale.

A tigbo lenu awon Babalawo wipe awon irunmole ko nsaba ba ara won rin po. Sugbon nwon so wipe Obatala ati Elegbara a ma ba ara won rinpo lopin odun meta-meta, awon Babalawo miran si so wipe lodun meje-meje ni irin ma npa won po eyikeyi to wu ki o je, e jeki a ma ba itan wa niso.

Otele-moja-Opo
Afakale-gboro
Awodi nla, omo aforabata
loju Olorun
Awon lo sagede fun
Otito ti nse omo Oduduwa
Ti yio di Oloro titi odun.

Owonrin meji.

Lojo kan Otito jade nile, o nlo si Oko, bi o ti nlo beni o se konge, Elegbara ati Olobatala. Elegbara wi fun Obatala wipe on yio so okunrin yi di olowo ati oloro lodun ni. Obatala dahun wipe, ki Elegbara jeki on fun okunrin na ni owo, nitoripe Elegbara ko mba ni gbe omo ye, bi o ba fun enia lowo, on na ni yio tun gba a pada.

Elegbara so wipe. owo ti ko to owo ni agbana nwo on yio fun okunrin na ni owo ti o joju-Laifa oro gun, Otito di Olowo, o kole, o kan-ase. iyawo mefa lo ni, sugbon koiti to odun meji owo poora, awon obinrin re kori sile won bayi ni Otito tun pada sinu ise ati iponju.

O si tun se bi Otito ti fun nlo si oko, o tun pade Obatala ati Elegbara, nwon bere kilo ti lowo ti nwon fun si? O si dahun wipe, owo na ko mo ni lowo. Elegbara tun fun ni owo ti o joju bakanna gegebi ti isiwaju, owo na tun poora. Nigbati o pe asiko igba meta ti Elegbara nfun Otito ni owo giri-moyan ti Otito ko si tilori re la, nigbana ni Obatala wa gba ira.

Bi teni yio ba suwon
Araiye ko nile ba a je
O difa fun Otito omo Oduduwa
Ti yio fi Esu sile lati
Ba Obatala sowo po

Owonrin meji.

Otito je asegi ta. Lojo yi ti o nlo si oko lati segi, o pade Obatala, o si so fun wipe, ki o segi pupo wa sile loni, Otito gbo, o si lo si oko ki o to dele, ojo nla kan ti ro ni Ile Ife eyiti o da oiutu sile ti gbogbo enia si ngbon tenutenu, gbogbo igi inu ile ni ojo yi pa ti o si so di tutu, gbogbo enia wa igi lati ra, nwon ko ri.

Bi Otito ti ru igi wo ilu wa, beni won surubo o, were-were o ti ta igi yi tan, osan ko iti pon, o tun kori si oko, laifa oro gun, oke meta owo li o pa lojo na.

Lojo keji Otito tun lo fo aso lodo, o si ri okunrin kan ti o nsokun leti odo, o bere kini o se o? O dahun pe Iwo kan soso ti on ni lowo ni eja nla kan ja lo, on ko si lowo lati ra omiran. Otito wi fun pe, emi ni Iwo kan nihin, bi o ba le se ileri pe eja keja ti o ba koko pa, temi ni yio je, ngo fun o ni Iwo na. Apeja na si gba be, Eja ti o koko pa, o gbe fun Otito.

Nigbati Otito dele, o ba imi Osumare ninu eja na. Nigbati Oduduwa gbo, o gba a lowo re, o da lole, o si fi je oye tobe, nigbati Oduduwa takun lo s'orun, on lo koko joba ni Ife. Ade re ni a npe ni Ade Otito titi di oni.

WESTERN REGIONAL PRODUCTION DEVELOPMENT BOARD

## JUNIOR ENGINEERING ASSISTANT GRADE I

Applications are invited from suitably qualified candidates to fill a vacant post of Junior Engineering Assistant Grade I in the Board's Engineering Department.

Applicants should posses sound mechanical knowledge of Land Rovers, Ferguson Tractors and Bedford Commercial vehicles, and should show evidence of having undergone a recognised course of technical training in one of the Region's Technical Institutes.

The selected candidate will be required to tour and carry out normal maintenance work on Board's vehicles including Ferguson Tractors, etc.

Salary will be in the scale £195x15-300 per annum, point of entry depending on qualifications and experience.

Applications, accompanied by copies of certificates and testimonials should give particulars of age, technical training, present appointment and should be forwarded to reach the Personnel Secretary, Western Regional Production Development Board, Ibadan, not later than 15th September, 1955.

## Alhaji Hakeem Orun re !

Kosi bot/je ni fun gbogbo enia ati awon Ijo Ahamadiyya pataki l'Eko ati ni gbogbo ile "K'aro eo jire" nigbati a gbo iku Alhaji Maulana Hakeem, eniti ise okan pataki ninu awon to fi idi esin Muslim mu'le l'ona ti Ahmadiyya.

Alhaji Hakeem wa si ilu wa ninu odun 1922, gegebi oluranwo fun Ologbe Alhaji Mualana A.R. Nayyar "(Ki Olorun fi si afefe rere), lehin na ni nwon gbe lo si ilu Aganyin, (Gold Coast) nibe ni o wa fun odun meje gbako, ise re to se nilu Aganyin larin odun meje na ko kere. Opolopo enia l'o fa sinu Ijo Ahmadiyya, o si ko to ogorin Mosalasi, o tun ko ile-eko (School) ti Olotu Eko ti Ijoba Gesi fi kan sara iyin si.

Ninu odun 1934 l'o tun pada silu wa nihin, gegebi Olotu Ijo Ahmaddiyu, o si wa nilu Eko nihin titi di odun 1947, ni asiko igbana, rogbodiyan mbe larin Ijo, eyiti o gbona depo ti o fi je wipe ile ejo ni oro na gbe sole si, Ologbe Alhaji Hakeem yi si se gudugudu meje ti o fi ese esin Muslim l'ona Ijo Ahmadiyya duro, ti a fi ri ile gbigbe fun awon Olotu Ijo na bi No-21 ati 23, ti o mbe ni Ojo-Giwa Street, loni. (Oko-Awo)

Alhaji Hakeem yi je olufokansi pataki ti o fi gbogbo ojo aiye re sin Olorun lododo, o si je Oniwasi oro Olorun titi ojo aiye re fi d'opin ninu esin Musulumi.

Ki Olorun d'ele fun u, ni adura tiwa.

ENJOY YOUR OWN SONGS



SUNG BY YOUR OWN PEOPLE IN THE WAY YOU LOVE MASTERLY RENDERING OF TRADITIONAL AFRICAN MUSIC IS YOURS NOW

OBTAINABLE FROM :

The Association Of Nigeria Gramophone Dealers

THROUGHOUT NIGERIA

## Qgongo Bori Erin Abuse-buse

KABIYESI O!



QBA ALAIYELUWA— OLU-EPE

EpE— Ninu ibo ti a di fun atiyan enia, sinu Igbimo Ibile ilu Epe ni ojo karun osu yi; Egbe Faramora ni o bori. Egbe Ijebu Parapo gbiyanju won ni enia Metadinlogbon (27) ti Egbe Faramora je mejidinlogbon (28).

Olu Epe ti o je Baba-Egbe Faramora ni yio se Alakoso (President) Igbimo Ibile ilu Epe na.


### Kere o!

A ti ni orisirisi ogun Germany to sese de, fun orisiruru aisan tokunrin tobinrin. Tete wa ra tire ko to tan.

J. A. AJAO BROTHERS
Medicine Store
7, Egerton Road, Lagos



**Polowo Oja RE Sinu Iwe Irohin Eleti-Qfe**



**Plushes, Velvets, Velveteen, Damasks & Building Materials**

PLEASE CONSULT :

**Okunowo Brothers**

63, Massey Street, (Ebi Market)
LAGOS, NIGERIA.
The house where Courtesy & Satisfaction are Guaranteed


## Okunrin Kan Pa Baba Egbe Nitori Ipo Re

PANAMO— Okunrin kan ti o nse baba Egbe fun Igbimo Ibile Panamo ni okunrin odelesinrin kan yinbon si, ti o si pa ni osangangan sugbon ki apania yi to salo owo olopa te.

Nigbati nwon mu de Sabu awon Otelemuye oni ki nwon se on jeje, Loya ti o nse igbakeji Baba egbe Igbimo ni o ran on lati sise yi,

Gere ti Baba egbe yi ku ni awon Igbimo ranse pe Loya yi wipe ki o wa bura ki o si bosi ori aga igbimo. Nibiti o nfe bura ni awon Otelemuye gbe yo si, nwon si ko panpe da si ni owo, elomiran ni o tun pada je oye Baba egbe na. Oro na si wa ninu Kotu, nwon ko si gba iduro fun Loya, ati apania na.


# AWO IKQRIN (RECORD) TI DECCA

yio mu awon orin ti o fe ati awon akorin wa sinu ile re

**Lo ra won ni sobu S. C. O. A**

A ti da Eka titun kan sile ti yio tete ma fi awon eru ti o se pataki ranse

S. C. O. A.



**Head Office:- 40, Marina, Lagos.**
**Show Room: Martins/Broad Street, Lagos,**
ATI NI
Ibadan, Sapele, Warri, Onitsha, Calabar, Aba, Port Harcourt, Kano, Enugu, Zaria & Sokoto.

# BUMPER OFFER

## EACH COMPETITION BEARS INDIVIDUAL GUARANTEED PRIZES

**£1500** FOR EACH ALL CORRECT.

**£100** For each first two horizontal rows correct.

**£5/-** for each first one horizontal row correct.

**£1/-** For each two horizontal numbers correct.

| | | | |
|---|---|---|---|
| | | | |
| | | | |
| | | | |
| | | | |

Arrange numbers from 2 (two) to 17 (seventeen) in the squares so that the total should be 38 (thirty eight) when added vertically, horizontally and diagonally. Each number should be used once only.

Last Result

| | | | |
|---|---|---|---|
| 9 | 3 | 14 | 8 |
| 16 | 6 | 11 | 1 |
| 4 | 10 | 7 | 13 |
| 5 | 15 | 2 | 12 |

ENTRANCE FEES :- Sh. 4/- for one entry or Sh. 28/- for each set of eight entries or £10/- for each set of sixty four entries.

**£1500** FOR EACH ALL CORRECT.

**£200** For each first one horizontal row Correct.

**£1/-** for each first one number correct.

Arrange numbers from 1 (One) to 101 (One hundred and one) in the squares so that the total should be 153 (one hundred & fifty three) when added vertically, horizontally and diagonally. Each number should be used once only. The position of the number 51 remains unchanged.

| | | |
|---|---|---|
| | | |
| | 51 | |
| | | |

Last Result

| | | |
|---|---|---|
| 79 | 26 | 45 |
| 16 | 50 | 84 |
| 55 | 74 | 21 |

ENTRANCE FEES :- Sh. 4/- for one entry or Sh. 28/- for each set of eight entries or £10/- for each set of sixty four entries.

LAST POSTING DATE (from your place)-(*By Air Mail*) 26-9-55 RESULTS : 11-10-55

*RULES for both the competitions:- A competitor can take part in any one of the competitions or both provided respective requisite fee at the above rates is sent along with the entries of each competition. Any number of entries on plain paper are accepted. Fees as well as entries of both the competitions, but made on separate papers, may be sent together. Attach British Postal Orders or Bank Draft or Money Order receipt, payable to EASTERN TRADE & FINANCE, NEW DELHI-5, as fees with Entries. Write your name and address in the Entry sheet clearly. Use English figures for the solutions Correspond in English only. One person is eligible only for one (highest possible) prize in each competition but if a competitor is declared to be an all correct prize winner in both the competitions at a time, he is entitled to get an extra special award of £100/-.*

*The solution or the rows are said to be correct only if they are similar to our official sealed solution or to its corresponding rows which will be opened in our Office on the Result's date. Add Shilling 1/- more in your entry fee for the result which will be communicated (by Air Mail) within a week after its declaration. The promoters' decision shall be final and legally binding in all respects and is an express condition for entering this competition.*

Address your Entries with fees to :-
EASTERN TRADE & FINANCE (141) Ramjas Road, NEW DELHI-5 (India).


# Sport Today
## RAILWAY Vs SCOA

Since the defeat of UAC by the Railway last Saturday in the Challege Cup Competition, the talk of the town is which team will represent the Federal Capital or capture the Pilot cup The question will be answered today when the two teams meet on our Local Wembley There is no doubt that Railway team stands a better chance. Rail's victory of 5-2 over UAC last weak is still fresh in our memory. A large number of fans have of late been impressed by Rails regular brilliant display and if they continue to improve upon their weapon of attack, they will eventually snatch both the Pilot Cup and the most coveted- NIGERIA CHALLENGE CUP.

As for the SCOA, they have got a formidable defence of Ifedira, Sulaimon and one Way Alabi Ntephe in the half line- but can they stop fast moving Ben, Ironkwe and Henshaw in the Rails forward line? The answer could be given in the affirmative provided they play cohesively and intelligently.

Many fans will be left to recall the popular saying "How are the mighty fallen" if either the Railway or SCOA win this cup match today May the better side win.

WELCOME REGIONAL TEAMS

The Regional Champions Portharcourt. (East), Warri (West), and Kano (North) will arrived in town next Wednesday. It will however be recalled that since the competition started, Portharcourt came to Lagos only once Warri twice and Kano thrice. The three teams will be lodged by the Nigeria Football Association.

## Alakoso Ijoba Ilu Aganyin De Si Okun Eko

Dokita Kwame Nkrumah, ti ise Alakoso Ijoba ilu Aganyin, (Prime minister of Gold Coast) ba oko ti a npe ni Nigerstroom de si okun ilu wa yi, o si ti so fun ijoba wa (Federal Government) wipe on ko fe ki enikeni wa ri on.

Alakoso Ijoba ilu awon Aganyin yi gba olofe-ara wa lati le sinmi die fun opolopo ise re, eyi ni ohun to fi so wipe on ko fe iyonu rara. Dokita Nkrumah yio se to ojo merin lori osa ilu wa nihin.

## Iwadi Igbimo Ibadan.

Awon eleri lorisirisi ni nwon njeri lo nitoni perewu, pataki oro eri awon ti o njeri lowo ni wipe Ogbeni Adegoke Adelabu gba owo ebin lowo awon, oloeun powun pelu garawa epo pupa kan nro tire, benani oni powun medogbon nro tire. Bi eleri ti nro ejo tan, beni awon Loya tun se ibere lorisirisi lowo won.

Bi oro iwadi na ba ti nlo si ni ao ma se irohin re fun enyin okawe wa ninu Iwe Irohin wa Eleti - Qfe yi.


A GIFT FROM HEAVEN!



BAMWO BABY MIXTURE
OF EXCEPTIONAL VALUE IN PREVENTING SICKNESS, CURING FEVERS, COUGHS, MEASLES AND TEETHING AILMENTS. ENSURES SOUND SLEEP.
PRICE: 2/6 POSTAGE 1/
THE EGBA TRADING AHADAN STORES. 144 DENTON STREET, P.O. BOX 2 ; EBUTE METTA & BRANCHES


Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street P. O. Box 467 Lagos Phone 23370